# AYÉ IJATILẸ AWỌN TI N GBÉ ODODO ARA WỌN KALẸ

**Romu 7:1-25**

**ẸKỌ 386 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Njẹ ẹbi kò si nisisiyi fun awọn ti o wà ninu Kristi Jesu, awọn ti kò rin nipa ti ara, bikoṣe nipa ti Ẹmi" (Romu 8:1).**

**I Ifihan Ẹ̀ṣẹ nipa Ofin**

1 A lo ofin igbeyawo fun apẹẹrẹ, Romu 7:1-6; 1 Kọrinti 7:39

2 Ofin ni n fi ẹ̀ṣẹ ọkàn hàn, Romu 7:7, 8; Galatia 3:19.

3 Ọmọ ọwọ jẹ alailẹbi titi di igba ti o di ẹni ti o gbọnju, Romu 7:9; Matteu 19:14.

4 Imọ Ofin ni i mu idalẹbi wá, Romu 7:10, 11; 3:20.

5 Mimọ́ ni Ofin, Romu 7:12-14; Orin Dafidi 19:7-9.

**II Ijakadi Lati Gbé Igbesi-aye Rere Lai si Ìbí Titun**

1 Ẹṣẹ jọba lori ara, Romu 7:14, 15, 17-21, 23; Johannu 8:34; Romu 6:16.

2 Ọkàn jẹri si ododo Ofin, Romu 7:16, 22.

3 Igbe fun Olugbala, Romu 7:24; Luku 18:13.

4 A darukọ Olugbala, Romu 7:25; Matteu 1:21.

## ALAYE

### Ofin Igbeyawo

Paulu fi ofin igbeyawo ṣe apẹẹrẹ ibi ti Ofin Mose ni agbára dé. Lode-oni awọn eniyan kò tun fẹ fi awọn ẹjẹ́ igbeyawo pe mọ́, ṣugbọn Jesu wi pe: "Ẹnyin ko ti kà a pe, ẹniti o dá wọn nigba atetekọṣe o da wọn ti akọ ti abo, O si wipe, Nitori eyi li ọkunrin yio ṣe fi baba ati iya rẹ̀ silẹ, yio famọ́ aya rẹ̀: awọn mejeji a si di ara kan. Nitorina nwọn ki iṣe meji mọ́ bikoṣe ara kan. Nitorina ohun ti Ọlọrun ba so ṣọkan, ki enia ki o máṣe yà wọn" (Matteu 19:4-6). Ẹnikẹni ti o ba kọ̀ aya rẹ̀ silẹ, bikoṣepe nitori àgbere, ti o si gbé omiran ni iyawo, o ṣe panṣaga: ẹnikẹni ti o ba si gbé ẹniti a kọ̀ silẹ ni iyawo, o ṣe panṣaga" (Matteu 19:9). Gẹgẹ bi ofin Ọlọrun ati gẹgẹ bi apẹẹrẹ ti a lo lori iwe yii, igbeyawo wa "titi ikú yoo fi yà wá." Lati fi ominira ti obinrin ni lati ṣe igbeyawo lẹẹkeji lẹyin ikú ọko rẹ̀ hàn, Paulu sọ fun awọn arakunrin rẹ̀ ti o mọ Ofin ti a si ti fi Ofin dè pe wọn di ominira nisisiyii kuro labẹ Ofin nipa ikú Kristi. Ṣaaju o wi bayii pe: "Bẹli ẹnyin ara mi, ẹnyin pẹlu ti di okú si ofin nipa ara Kristi ki ẹnyin ki o le ni ẹlomiran." Ẹnyin di oku si Ofin, tabi ki a sọ ọ ni ọna miiran ẹyin ko si labẹ Ofin mọ́. Nigba naa ni ó tún tún ọ̀rọ naa sọ lọna miiran bayii pé Ofin ti kú. "Ṣugbọn nisisiyi a fi wa silẹ kuro ninu ofin, nitori a ti kú si eyiti a ti dè wa sinu rẹ̀." Nipa bayi a ri i bi a ti di ominira patapata kuro ninu Ofin Mose.

Ni ikú Rẹ̀, Kristi mu Ofin ṣẹ, O si sọ awọn ti o wà labẹ Ofin di ominira, ki a le so wọn pọ pẹlu Rẹ̀ nipa ajinde Rẹ̀. "Nitori Kristi li opin ofin si ododo fun olukuluku ẹniti o gbagbọ" (Romu 10:4). Nisisiyii ti Ofin ti di okú, a le sin Oluwa ni "ọtun ẹmi, ki o má ṣe ni ode-ara ti atijọ." Nipa gbolohun yii a le rii bi awọn Ju ti kuna labẹ Ofin. Wọn pa a mọ ni "ode ara ti atijọ" dipo nipa igbagbọ́ ní "ọtun ẹmi." Nigba kan ri ti wọn ti n mu "eso wa si ikú" nisisiyii wọn yoo maa "mu eso wa fun Ọlọrun" Iyatọ nlá nlà!

### Agbara Iṣipaya ti Ofin

Ofin funra rẹ̀ ki i ṣe ẹṣẹ, ṣugbọn o n fi ẹṣẹ ti o wà hàn ni ti pe o fi awọn aṣẹ fun ni ni pato bayii pe: "Iwọ kò gbọdọ ṣojukokoro." Ti a ba fi oju iwa ọmọluwabi wo o, kò tọ́ lati ṣe ojukokoro, bi Ofin ko ba tilẹ wi bẹẹ. Ṣugbọn Ofin fi ẹṣẹ ojukokoro hàn. Ki Ofin to de, Paulu wi bayii pe, "Mo wa lãye." Itumọ rẹ̀ ni pe n ko mọ ẹbi ẹṣẹ titi di igba ti a fi hàn fun mi pe ko tọ́ lati ṣojukokoro. Ẹri ọkàn rẹ̀ sọji nigba ti Ofin dé, ti o si ri i pe o kọja agbara oun lati gbe igbesi-aye bẹẹ. "Ẹṣẹ ti ipa ofin ri àye, o tàn mi jẹ, o si ti ipa rẹ̀ lu mi pa." Mimọ́ ni Ofin o si dara, ki i ṣe Ofin ni o mu iku wá, ṣugbọn o ṣi ẹṣẹ paya, eyi ti n ṣiṣẹ iku. "Ofin ti a ṣe fun iye, eyi li emi si wa ri pe o jẹ fun ikú."

### Ofin Bá Ẹri-Ọkan Sọrọ

"Nitori awa mọ̀ pe ohun ẹmi li ofin: ṣugbọn ẹni ti ara li emi, ti a ti tà sabẹ ofin." Nigba ti Paulu kọ ni imọ Ofin, o mọ ododo rẹ̀. Ifẹ kan si wà ninu ọkàn rẹ̀ lati pa a mọ nitori ododo ti o wà ninu Ofin. Tinutinu ni o fi jẹwọ Ofin – o si pinnu lati pa a mọ, Ṣugbọn o ri i pe, oun kò le pa a mọ ninu agbara oun. Pẹlu gbogbo akitiyan rẹ̀ ni ipo aidi atunbi o ri i pe oun jẹ alailagbara, oun si n dẹṣẹ. O wi bayii pe: "Inu mi sá dùn si ofin Ọlọrun nipa ẹni ti inu: ṣugbọn mo ri ofin miran ninu awọn ẹ̀ya ara mi, ti mba ofin inu mi jagun ti o si ndi mi ni igbekun wá fun ofin ẹ̀ṣẹ."

**Isinru Ẹ̀ṣẹ."**

"Ara Etiopia le yi àwọ rẹ̀ pada, tabi ẹkùn le yi ila ara rẹ̀ pada? bẹ̃ni ẹnyin pẹlu iba le ṣe rere, ẹnyin ti a kọ́ ni ìwa buburu?" (Jeremiah 13:23). Ẹsẹ Iwe Mimọ́ yii fi idi ẹri Paulu mulẹ bi ko ti ṣe e ṣe lati ṣẹgun ẹṣẹ lai di atunbi. Ọna kan ṣoṣo ni o wà, oun naa ni lati fi irẹlẹ wá si ẹsẹ Agbelebu, ki a si bẹbẹ fun aanu. "Ẹ̀jẹ Jesu Kristi Ọmọ Rẹ̀ ni nwẹ̀ wa nù kuro ninu ẹṣẹ gbogbo" (1 Johannu 1:7). "Emi ẹni oṣi! tani yio gbà mi lọwọ ara ikú yi?" Iru ipo oṣi yii ni Paulu wà nigba ti o ni imọ Ofin ati ṣaaju ki o to di atunbi. Iru ipo ti ọpọ eniyan wà lode-oni ni eyi, awọn ti o ni imọlẹ Igbagbọ́ ti wọn si n fẹ rin ninu rẹ̀ lai di atunbi. Awọn miiran tilẹ n wi pe ijakadi ti Onigbagbọ́ n jà lati bori ẹ̀ṣẹ ni eyi. Bi o ti wu ki o ri, igbesi-aye Onigbagbọ́ ki i ṣe ti oṣi tabi ijatilẹ, bi ko ṣe igbesi-aye aye iṣẹgun ti ominira kuro labẹ isinru ẹ̀ṣẹ. "Ẹnikẹni ti o ba ngbé inu rẹ̀ ki idẹṣẹ; ẹnikẹni ti o ba ndẹṣẹ kò ri i, bẹ̃ni kò mọ̀ ọ" (1 Johannu 3:6).

**Iyatọ ti o Wà ninu Igbagbọ Ọgbọn-ori ati Ironupiwada Ọkàn**

"Njẹ nitorina emi tikarami nfi inu jọsin fun ofin Ọlọrun ṣugbọn mo nfi ara jọsin fun ofin ẹ̀ṣẹ." Njẹ a le wi pe ipo ti Paulu wà ni eyi lẹyin igba ti o di atunbi? Njẹ idande ti Kristi kú lati mú wa ni eyi? Njẹ itumọ ohun ti angẹli ni wi ni eyi nigba ti o sọ bayi pe: "On ni yio gbà awọn enia rẹ̀ là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn" (Matteu 1:21) Njẹ ohun ti Peteru tọka si ni eyi nigba ti o sọ nipa "idariji ẹṣẹ" (Iṣe Awọn Apọsteli 2:38)?

Awọn ti o n fi eyi pe iriri Onigbagbọ́ lẹyin ibi titun kò ti i mọ ayọ̀ idariji. Wọn kò mọ igbesi-aye "ẹbi ko si" ti Paulu sọrọ nipa rẹ̀ ni ori kejọ Iwe Romu. Fifi inu jọsin fun ofin Ọlọrun ati fifi ara jọsin fun ofin ẹ̀ṣẹ ki i ṣe isin tootọ si Ọlọrun. Jesu wi pe; "Ko si ẹniti o le sin Oluwa meji" (Matteu 6:24). Igbesi-aye ijatilẹ ati oṣi yii jẹ́ ti gbigbe ododo ara ẹni kalẹ. Ọpọ eniyan ni o wà ti wọn n fi ọgbọ́n-ori gbà pe rere ni ofin Kristi. Wọn fi ẹnu jẹwọ Kristi bi Olugbala wọn, ṣugbọn wọn kò ni iyipada ọkàn ti o le mu wọn gbé igbesi-aye iṣẹgun. Wọn n gbiyanju lati ṣe rere, ṣugbọn wọn n ṣubu nigbakuugba, wọn gbà pe Ihinrere dara, ṣugbọn agbara lati ṣe e kò si ninu wọn.

"Ki iṣe gbogbo ẹniti npe mi li Oluwa Oluwa, ni yio wọle ijọba ọrun; bikoṣe ẹniti nṣe ifẹ ti Baba mi ti nbẹ li ọrun. Ọpọlọpọ enia ni yio wi fun mi li ọjọ na pe, Oluwa, Oluwa, awa ko ha sọtẹlẹ li orukọ rẹ? ati orukọ rẹ ki a fi lé awọn ẹmi èṣu jade? Ati li orukọ rẹ ki a fi ṣe ọpọ iṣẹ iyanu nla? Nigbana li emi o si jẹwọ wi fun wọn pe, Emi kò mọ́ nyin ri, ẹ kuro lọdọ mi, ẹnyin oniṣẹ ẹ̀ṣẹ" (Matteu 7:21-23).

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni nnkan ti o le mu obinrin ṣe igbeyawo lẹẹkeji ki o má si jẹ́ panṣaga?
2. Ki ni itumọ ọrọ yii "ki ẹnyin ki o le ni ẹlomiran" ti o wà ni ẹsẹ kẹrin iwe Romu ori Keje?
3. Ki ni n ṣiṣẹ ikú fun awọn wọnni ti o wa labẹ Ofin?
4. Ki ni ohun naa ti n fi ẹ̀ṣẹ hàn fun awọn wọnni ti o wà labẹ Ofin?
5. Ki ni ṣeti Paulu kò fi le ṣe ohun ti o fẹ ṣaaju ki o to ri igbala?
6. Ọna wo ni igbesi-aye awọn ti wọn fẹ ṣe rere ti wọn ko si le ṣe e lode-oni fi jọ ti Paulu?
7. Ta ni le yọ wọ́n ninu ijakadi yii? Bawo?
8. Ki ni itumọ ọ̀rọ yii, "Ki awa ki o le mã sìn li ọtun ẹmi, ki o má ṣe ni oode ara ti atijọ"?